## Akiyesi

Anfe Eniti yio ma ba wa ta Iwe Irohin-Imole. Ni agbegbe Ilorin tabi Ilumiran. E lo si odo Ogbeni:- A. O. AJIBOYE Esq Ni Oja Gambari Ilorin

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

EGAN NI HE, BABA NI BABA NJE

6th & 7th Books of Moses lede yoruba 15/-, Iwe asiri Oba Solomon 20/-, Iwe ala Josefu 5/-, Iwe Asiri Oba Dafidi 20/-, Lilo a ti agbara Psalm 5/-. Iwe itaja ofe.

KERUBU & SERAFU BOOK-SHOP
15, Arzoti St. Yaba Nigeria

VOL. III No. 133 MONDAY J.NUARY 18 — JANUARY 24 1960 KOBO KAN (1d)

Ijoba Apapo wa mu oro tete tita lori bolu ti won ngba losese nilu oyinbo ni lile wayi.

# Ofin titun lori tete Bolu (Ball) gbigba ilu oyinbo

Orisirisi ona ni won ngba ta tete yi, okan ninu re nje FIXED ODDS, eleyi si ni pe awon ti o nta tete a ni ki o mu ayo meta tabi merin ti won ko ni na ara won, pe ti o ba mu ki o fi silekan ta, wa gba poun meta lori silekan. Ijoba Apapo fe ki gbogbo awon onile tete wonyi ni Eko fihan awon pe awon ni to egberun ogun poun ni ile ifowo pamo si (Bank). Eleyi ni won gbodo se nipa gbigba iwe eri lowo awon onile ifowopamo si pe awon ni owo ti o to be nipamo.

Nisinsinyi Alase Ijoba ti eto arin ilu ti fi iwe sowo ranse si gbogbo awon onile tete pe Ijoba fe se eleyi ninu iwe na Ijoba fihan pe awon fe ki won se nkan wonyi.

(1) So pe bi won ba fe ki Ijoba fun won ni iwe eri (Licence) labe Ofin titun ti Ijoba fe se.

(2) Ki won fi iwe eto won ranse si Ijoba

(3) Ki won so alabasise po melo ti ko si labe won ni tara' ni won fe.

Iwe Ijoba na tun toka si pe gegebi oye ti fifian ni ilu Gesi ati nibomiran o ye ki Ijoba da abo bo awon ara ilu ti o nta tete nipa pe ki won ma padanu owo won ti won ti won ba fi ta tabi ti won ba je nipa tita.

Nitori eleyi ni ijoba se ie se wipe awon yio fun awon onile tete ni iwe eri fun die, ati awon ti o je egbe ti o lowo lowo.

Nisinyi o ju ogun lo ti o ni iwe eri tete (Fixed Odds ni Eko

Ofin tete ti Ijoba se ni odun tokoja ko kuku menu le iru nkan bawonyi, o kan so wipe gbogbo eni to ba ni ile tete gbodo gba iwe eri ti owo re je Igba Poun £200 atipe awon alagbase Adota Poun (£50 for Agents) ninu gbogbo ile ti won ba ti nse ise tete, kosi eniti a ni ko fi owo kankan lele nitori owo ti won ba pin je owo ti won pa ni ose.

Nigbati a bi Ogbeni C. E. Wool Lewis Akowe Eto Arin ilu pe boya iwe eri wonyi awon omo Najiria ni-kan ni a o fun, o mi ori o dehun o wipe awon a ma ro o, sugbon o wa se afikun pe labe Ofin ti odun toko-ja awon ko fun ajoji kan ni iwe ri.

Firifiri kan ti a rigbo so wipe Alase Eto Arin ilu Mallam Usuman Sarki yio soro nipa Ofin titun ninu ipade Igbimo ti a nse lowo yi.

## Ha! eti re melo?



Eyi yi ni Ero Alata todaraju gbogbo eyi ti won ti nlo tele rilo leyin ata lilo o tun le lo Igbado ati Oka Baba ati Ewa - ere orisirisi.

**£45 Ni a nta** Pelu Enjinni Petrol tabi ati pelu Eletiriki Muto.

O WA NI SOBU:-

**Akoshile Brothers,**
5, Balogun Street West,
P. O. Box 599.
Phone No., 24395. LAGOS.

## MOGBAYI BABY MIXTURE
OLURANLOWO FUN AWON ABIYAMO




MOGBAYI BABY MIXTURE je ogun pataki ta se ni Asepe fun Awon omode, ati nlo ogun yi fun opolopo odun sehin pelu idaniloju fun Awon ise ribiribi ti o ti ose. MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi to dara pupo fun igbona iko, otutu Aiperi. Osi inu omode, jedi jedi Kokoro ori omode. O dara fun omode ti ko tete rin ati fun awon aisan miran bebe lo. O nmu ki omode ma nsun fonfon, o nmu ki ehin hihu je iro tun tun awon omode, osi njeki awon omode lobi, osi nmu won dan ni awo. Enyin Abiyamo, eku afojuba egbogi yi. Aran sin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi ti ko se mani fun awon omode. Ijafara lewu pupo, tete lo ra ti e ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo re.

Igo kekere re je 2/6d Igo nla je 4/6d
LILO RE:- Sibi kekere kan lemeta lojumo

*Wholesale Distributors*
A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS

6, Balogun Street West Lagos Nigeria. Phone 22515
34, DocemStreet Lagos Phone 204247

## O BERE 1 ATI OJU EWE KEJI

o wun on paapa, sugbon kosi owo lowo on. Arowosaiye wa mi o i titi, o ni iwo ore mi, kini kan ni awon yio se, ti o ba di ale, ki awon mejeji jo lo, ki a wo aso orisi aso kanna, fila be, Sokoto, bata, ki o wa tanse si omo na.

Nigbati o di ale, nwon lo si ile omo na, sugbon Gbajumokite wa ro oro na wo, o ni tani ninu awa mejeji ti o fe fe omobirin na. Arowosaiye si dahun wipe on ko se ore debi ti iyawo, ni ti on o, eniti omo na ba so wipe o wun on ni ko si ijo ni be.

Ni won ba wa Omo na lo si Ile re. Nigbati nwon de ibe, won pe omo na, Arowosaiye lo ko ba omo soro pe on fe fe o. Omo na si fun lesi pe ko buru.

Sugbon ko lo so fun iya on na: nibiti omo na ti fe pehinda ni Gbajumo-kite ba pe omo na, oni "Olufe mi lowon, mo fe ri yin fun iseju kan, oni oro ti fe ba yin so nipe, on fe ki on pelu yin jo je Toko-taya.

Omo na si dahun pe "o ni ese pupo, Olorun yio ran yin lowo. A fi ti e ba le ra ago-owo fun on loku, Gbajumo-kite wa bu serin muyeo, o ni, se ago na tabi o ku nkan miran ti o tun fe ra, omo na lotan.

Gbajumokite wa so fun omo na pe bi "Arowosaiye ba de odo re, ki o damu re dada." Laiko mo pe Arowosaiye ti de eba odo nwon.

Laifa oro yi gun, bi Gbajumo-kite ti so be tan ni Arowosaiye ba yo si lojiji ni Oro badi womi nwon. Ija ba de ni awon mejeji ba da ku lesekanna.

Ejowo, Eyin Okawe yi, "Ta l'oye ki Omo yi fe? ti Babalawo, ba ji awon mejeji tan ninu won, ki o fe? Arowosaiye tabi Gbajumo-kite ni?

Olotu, modupe, fun aye ti e gba mi, oko Oba ko ni ba yin o. Amin.

Lati Owo:—

J. ABIOYE OYEDARE
EKO.

## E ma ka Iwe Irohin Imole ki e ma pol-wo oja yin sinu re

## E jeki Elewon Gbegbe

Olotu/Yio je didun inu mi ti e ba gba mi laye lati ti oro kekere yi to awon onkawe yin leti

Oro na ko po, sugbon mo fe ki a gbe yewo, nitori gbogbo wa ni o ba wi, oro na ni nipa ti igbe gbigbe l'Eko gegebi ati ngbo won ni Oba awon Egbe tio ngbe igbe lo ranse si awon enia re pe abuku lo je fun on ati ilu on pe awon omo Egbe lo ngbe igbe ni Eko, atipe o ti da oju ti on ni awujo awon Oba pe on je Oba agbegbe.

Bi otito ni oro yi emi ko mo, sugbon oye ti mo ko nipa re nipe emi papa ti si pe ki a fi igbe gbigbe se ise se.

O ye o si to pe ki awon elewon ma fi gbe gbigbe se ise, inu awon elewon ti mo nro lokan nigbati mo nko iwe yi ni awon ole ati gara ti won ko nje ki ilu ni alafia.

Mo fe ki Ijoba gba oro yi yewo ki won si mu se, nigbati awon ole alagbara ma sise ba nri pe igbe ni elewon ngbe, won a lo we ise se, won a si dekun ole jija.

Mo lero pe eyin onkawe Irohin Imole yio ri si oro mi yi, mo si lero pe e o ko iwe si iwe Irohin yi, lati gbem lese

Emi ni
Ibilola Abeke

## Kilofa idi Oro yi.?

Olotu./ Jowo gba mi laye ninu Iwe Irohin re Oloyin momo, lati bere lodo awon Okawe re, kini ohun to fa ababi ti nwon fi npe gbogbo eniti o ba nje Oruko nwonyi ni Oruko miran boyi:

Ese ti nwon fi npe gbogbo Sal mi ni Apaje gun-ori-Ite.? Ese ti nwon fi npe Adeniji, ni Apata tabi Sinsba.? Ese ti nwon fi npe Adamo, ni Akeji.

Ese ti nwon fi npe Buraimoh, ni Elekun, tabi Deede Elekun.

Ibere mi na po die, sugbon, ejeki a ma bere die-die. Odigbo se.!

Emi ni,
JANSON.
Ara Okokomaiko. N.g



